# Christ apostolic Miracle Ministry

## Eko Ojo Isimi fun Odun 2016

## Ikini Ati Afihan

Ope ni fun Olorun loke orun, ti ose ade abo lori wa ti osi da emi wasi lati ri odun tuntun ni ile alaye.

Agbadura wipe iwalaaye wa koni je idalebi niwaju Oluwa.

Orisun oro Olorun ninu aiye wa koni gbe, besini Oludumare ninu anu re yio fun wani okan irele ati ironupiwada.

A o se opo odun laiye, ninu alafia ati ayo Olorun ni oruko Jesu. Amin.

E ku odun tuntun. 2016

# Christ apostolic Miracle Ministry

## Eko Ojo Isimi fun Odun 2016

### Ose Kini: Osu Kini Ojo Keta 2016

**Akori Oro** : Eso Akoko

**Eko Kika:** Deuteronomi 26: 1-11

### Afihan

Gegebi ase mo wipe Olorun wa, ohun ni Olorun ninu orun ati lori aiye, ti asi mo wipe “ti Oluwa ni ile ati ekun re; aiye ati ohun gbojbo ti o tedo sinu re, eyiti o tumo si wipe gbogbo alaaye okan ati awon ohun tiko ni emi ti Olorun ni. (Orin Dafidi 24:1)

Siwaju si o se pataki lati mo wipe Olurun feran ohun akoko gidigidi, tori idi eyi ao soro nipa ife Olorun si ohun akoko.

### Ife Olorun Si Ohun Akoko

Dandan ni fun gbogbo okan lati fi pin fun Olorun ninu ohun ti Ogaogo se fun won. Eyiti o wa fun ipolongo ati idagbasoke ise Oluwa ni ile alaaye. Gegebi ati so siwaju,

Olorun feran ohun akoko ninu ohun gbogbo, idi re ti oruko re fi nje Alfa ati Omega eyiti nse **eni akoko** ati ikehin ti asi tun le pe ni ibere ati opin.

Nipa awon alaye ti ati se, ao ri wipe oye osi leto ki awa onigbagbo ya ohun gbogbo ti se akoko ninu aiye wa si mimo fun Olorun.
Etiyi o tumo si wipe akoko omo wa, eso akoko wa ati owo osu akoko ti aba gba ninu odun ti Olorun ni. Ni itesiwaju Olorun papa ni o yeki o je akoko ninu ero ati okan wa.

Olorun se afihan ife ti o nisi ohun akoko nipase omo bibi re kansoso Jesu Kristi Oluwa wa.

- Jesu Kristi ni eni **akoko** ti a loyun nipa emi mimo
- Jesu ni **akobi** Maria wundia (ohun na si ni **Okunrin akobi** Maria Mimo)

- Jesu yi kanna ni **akobi** ninu awon oku ati eni **akoko** ti o jinde.

Pataki afikun ni wipe nitori ife ti Olorun nisi Ohun akoko ohun ai o jeki o pa awa onigbagbo lase wipe ki ama mu akoso ere oko tabi owo osu wa fun ohun ni ododun, nigbati ohun ti o kusile tabi iyoku yio je fun itoju ara wa.

Olorun fi idi ase nipa ti akobi omo mule ni ile Egipti nipa agbara nla re. Tori idi eyi Olufokansin ti koba tele ase Olorun le kuna ile Ologo.
Toripe alaigboran kan ki yio wo ijoba Olorun bi otiwu ki ori. Ao soro ni kikun nipa kini ase Olorun lori akobi tabi akoso.

## Ase Olorun fun Akobi Tabi Akoso

Awa Kristiani ni lati setan lati se fun eleda wa ni kikun ni alaiyo sehin. Nitori idi eyi e jeki ama san idamewa, akoso ati awon ojuse wa pelu igbagbo.
Mo feki odi mimo fun wa loni wipe gbogbo awon akobi omo wa niti Olorun. Tori idi eyi ni ose fi abo bo awon akobi awon omo Israeli ni ile Goseni to osi pawon mo nigbati awon akobi awon ara Egipiti Igbani si segbe (**Eksodu 22:29**).

Ko si okankokan ti oni eto lati fi akobi re dun Olorun gegebi ohun ini Re. Ohun ti ale se nipe yala ki aya awon akobi wa si mimo fun ise Olorun tabi ki ase igbese lati rawon pada gegebi ase Olorun ninu Iwe Eksodu. (**Eksodu 13:11-15**).

O yeki oye yewa wipe ninu gbogbo awon ajodun ti Olorun fowosi, ajoyo akoso je okan pataki ninu won. Idi re ti ijo wa (Christ Apostolic Miracle Ministry) se nse Iranti ase yi ni rere. (**Eksodu 23:14-16**).

Akoso je ajodun ti gbogbo okan ni lati pejo niwaju Olorun, lati mu awon akoso ile wa, akoso ise owo wa ati akoko gba owo osu wa wasi iwuju eniti oda aiye ati orun.

Ni igbakugba ti aba mu awon akoso wasi iwaju Olorun, oni lati je pelu adura ati Idaraya. Eyi ni yio jeki akoso na se itewogba niwaju Olorun, Eniti yio si bukun wa tokan, tara tori igboran wa. (**Numeri 28:26**)

O se koko lati dunnu niwaju Oluwa ni akoko pataki yi, toripe Olorun feran oninudidun olore. Bi enia base pelu ikunsinu, ekun, paapa bi enia se lati se asehan ko se itewogba niwaju Oluwa.

## Ibiti Ao ti San Akoso

Iwe Deuteronomi fi idi re mule wipe ibiti a yonda tabi la sile lati gba akoso ni ile Oluwa. Nitiorina e mase san akoso ni ibomiran bikose ni Tempili Oluwa.

Ayafi ti enia bafi ranse tabi mu akoso re wasi inu ile ijosin ni iwaju Oluwa. Iru akoso be kose itewogba. (**Deuteronomi 26:2-10**).

Ibikibi ti ole wa labe orun, yala ile ibi re ni tabi ile ileri re, tabi ile imuse ogo aiye re. Ojuse re ni lati san akoso re ninu Tempili mimo Re, gegebi eniti nfi emi imore han ti osi nyo fun ohun gbogbo ti Oluwa tise fun.

E jeki a ranti wipe ati funmi O ni ibukun ninu ju ati gba lo, torina e jeki a san akoso wa fun Olorun eniti yio san esan ise rere yi.

## Awon Ti a Fifun Lati Gba Akoso

Nibiyi oye ki afi ye ara wa wipe awon alufa nikan ni a fifun tabi fun ni ase lati gba akoso. Ti aba mu akoso wa losi ile ijosin e jeki a san fun Oludasile tabi Olusoaguntan agbo wa.
Ko leto fun wa lati san fun awon osise ijo bi akorin tabi asona. (**Lefitiku 23:10**)

Ti oba feki Olorun mu awon ileri toku ninu aiye re se, o ni lati san akoso re fun awon ti o ye lati akoso.

## Awon Idi Ti Afi Ngba Akoso:

Olododo ni Olorun wa, idi niyi ti ofi wipe ohun nilo akoso fun awon olusoaguntan ati alufa. O mo wipe awon enia yi ko loko tabi odo, tabi ise miran ti nmu owo wole fun won bikose ise Oluwa. (Lefitiku 23:10) Ti o ba feki erin jade lenu awon idile alufa tabi olusoaguntan re, mo rowa ki a san akoso wa gegebi ase Oluwa niigba toto ti osi ye.

Siwaju si Olorun se itoni fun awon omo Lefi, ti won je osise ni ile Oluwa. Ki awon na ma pin ninu akoso. Niwon igbati Olorun korira imo-taraeni-nikan ti akoso si je ona ati mu itesiwaju ati igbega ba ihinrere larin awon alaaye okan. (Deuteronomi 18:1-4)

Bi e koba feki awon olusoaguntan wa se alaini tabi damu sugbon ki won ni anito ati aniseku. A ni lati ma san akoso wa ni ododun. Enikeni ti koba san akoso re iru eni be ko fe ilosiwaju fun ise Olorun.

## Olorun Fe Ohun Ti O Daraju:

A ni lati mo wipe ola ati oro ti ani ti Olorun ni, o kan fiwa sipo lati mase akoso won ni.

Ninu iwe Genesisi (Genesisi 4; 2-5) afi ese re mule nigbati Kaini mu eso ti ko fiyin fun Olorun wa sugbon Abeli mu **akobi** awon eran osin ti o sanra wa. Ni idi eyi Oluwa se ope Abeli ni itewogba sughon ope ti Kaini ni ko kasi.

Ase Olorun ni lati mu ore ti o daraju ati akoso eyiti nse ipin awon olusoaguntan wa, Nitori idi eyi e jeki a tele ase Olorun ki asi te eleda wa lorun.

Eyi ni yio jeki Oluwa fifun wa gegebi ero okan wa ki osi mu gbogbo ipinu rere wase ni kiakia. (Numeri 18: 12).

## IPARI

Lakotan gbogbo Kristiani ko gbodo gbagbe lati mu ohun ti o daraju ati akoso ile tabi ti ise owo tabi akoko gba owo osu won wa ni odun 2016 si ile Olorun.

Ki oba le dara fun won ki asi so won di pupo fun rere ni gbogbo ona won, pelu agbayanu alafia ni odun 2016.

## Christ apostolic Miracle Ministry

## Ose Keji: Osu Kini Ojo Kewa 2016

**Akori Oro** : Aigboran Apa kini

**Eko Kika:** Jeremiah 42: 1-18

## Afihan

Aigboran je aitele awon ilana tabi awon ofin ti afi lele. Lafikun awon alaigboran ni awon enia ti won kuna lati se ohun ti aba wi fun won tabi se ohun ti o leto ki won se nitori agidi okan won. Iru awon eya wonyi ni won nse awon ohun ti won kibati se won asi fi awon ohun ti o leto fun won lati se sile ni aise.
O je ohun ti ko bojumu lati se aigboran si awon alagba ati awon alase niwon igbati ohun ti won ba nfe ki ase kobati lodi si igbagbo wa gege bi kristiani. Ni igbakugba ti enia ba se ori kunkun lati se afojudi si awon alase nipa aise ohun ti ase wi tabi iwa aibikita fun awon ofin ti agbe kale, iru okan be nfi emi ara re wewu ambotori ki enia wase aigboran si Olorun.
Ni ilana eko bibeli awon alagboran ni awon ti won ndeja ti won si nse afojudi si Oluwa, Olorun Olodumare kosi ni wo irekoja yi gegebi ohun kekere. Oluwa yio ri gegebi wipe enia ti nse erupe npe Ase Mimo Re nija tabi o nri Ase Olorun fin.
Siwaju si aigboran yi je ese nla ti osi buru jayi atipe Olorun yio wo ese na gegebi oju ogbe ti ako ba mojuto ti yio ran ti yio si di ese nla ti apa le maka mo bi ako ba tete bojuto.

### OHUN TI AIGBORAN JE NIPA ILANA BIBELI

### AWON ALAIGBORAN NI ASORO ODI SI KRISTI ATI IRINSE SATANI

Ni igbakugba ti enia base aigboran si Olorun, won ngboran si Esu lenu won si nse ife re, atipe enikeni ti oba ko lati tele ase tabi ilana Imole iru okan be okunkun ni won ntele. Nitorina awa ni ao yan eyiti owu wa boya ki a te Olorun lorun nipa gbigboran si ase Re ni tabi ki ate Satani lorun nipa sise aigboran si Olorun.

Ohun kan ti a nilati mo ni wipe, okan kokan ti oba se aigboran si Olorun nipa yiya kuro ninu otito, didarapo tabi fifi owo sowopo pelu awon okunkun aiye. Iru okan be yio segbe pelu won loju aiye ati labe orun ni bibeli wi (Jeremiah 10:11).

Ti o koba fe pare mo aiye ti o kosi fe ku fun ota lati yo, ma se aigboram si Olorun tabi lowo si sinsin orisa tabi ebora.

## AWON ALAIGBORAN NDAN OLORUN WO

Awa Kritiani ni lati yago fun iwa aigboran, eyiti ole fiwa han bi eniti ndan Oluwa eleda re wo.
Mo be wa e jeki a keko lara Okurin ti nje Ussa ninu bibeli eniti a padanu emi re nipa aigboran si ofin ti o diromo Apoti-eri Oluwa.

Arakunrin Ussa yi eniti kise alufa nwa ona lati fi owo kan Apoti-eri, aye ati fi owo kan Apoti-eri si sile fun nigbati awon Malu ti nfa keke ti o gbe Apoti-eri kose.
Ussa na owo re osi di Apoti-eri mu eyiti ko leto lati fi owo kan, ose eyi bi eniti ko feki Apoti-eri jabo lule.
Si gbogbo awon ti won pejo, won ri Ussa bi eniti nse ise Oluwa, sugbon Olorun ti nse ayewo okan mo pe nse ni Ussa nse afojudi si Ohun (wipe moti fi owo kan apoti laise alufa) idi re niyi ti Olorun fi lupa lesekese (2 Samueli 6:3-7)
Tori idi yi e gbo ikilo, e mase dan Olorun wo tabi se afojudi si eleda yin. Nitoripe enia kole tan Olorun ti o mo o ju ara re lo, O mo awon ohun ikoko ati asiri okan awa eda enia.

## IGBORAN SAN JU EBO LO

Bibeli fi idi re mule wipe igboran san ju ebo lo, nitoto Oluwa ni inu didun si igboran ju ore ebo sisun lo, ni igbati aigboran tabi agidi si buru loju Oluwa bi iborisa (1 Samueli 15:22-23)
Awon alaigboran yi nse awon nkan ti ole mu Olorun binu, ki iru awon enia wonyi mase lero wipe awon yio ri ire gba lowo Oluwa, toripe enia kole ma posi ninu ese ki oreofe Olorun si ma bisi ninu aiye re.
Ara ninu Oluwa e jeki a gboran si ase Ouwa, ki asi tele ofin/ilana ti o fi lele ni gbogbo igba, ki o ba le dara fun wa ni iwon igba ti ao lo ninu aiye.

## AWON ALAIGBORAN KO MO OLORUN

## IJEWO ETAN

Kosi bi enia tile jewo wipe ohun mo Olorun to, ise iru okan be nikan ni ole fi idi ijewo yi mule. Toripe opo Kristiani ni won njewo wipe awon mo Olorun, sugbon ti won nse iwa-laaye Re nipa ise ati igbe-aiye won. Iru awon eya yi je eni irira, alaigboran alaileso ati alainilari niti ise rere gbogbo ti nbe labe orun yi (Titu 1:16). O je ohun ti o nsele pupo lode oni, wipe opo ti won wipe won mo Olorun ti won si nhun nwu iwa omoluwabi ni ile Oluwa. Ti e ba bawon pade ni ode iwa won, isoro won ati imura won ki fi ogo fun Olorun besini igbe-aiye won lodi si awon iwa Kristiani.

## E MASE PADA SI IGBE-AIYE ATIJO

Awa onigbagbo, ni igba kan ri tije were nipa ti emi ati alaigboran, ni awon akoko yi Esu tan wa, asi sako lo kuro ninu ife Olorun. A si je eru ti nsin oniruru ifekufe ati adun aiye.

Aiye wa nigbana kun fun iwa ibi, ilara ati orisirisi iwakiwa, a korira awon enia besini awon enia korira awa na, eyiti o fi aye sile lati ma yan odi. Sugbon ni isinyi a ti wa ninu Jesu Kristi ohun ti o so wa di eda titun besini ohun atijo ti koja lo (Titu3:3).

Ara ninu Oluwa, e mase jeki a pada si awon iwa atijo wa mo papa julo iwa aigboran. Toripe "o dara ki enia oma mo Jesu Kristi, ju ki o se lehin ti o ti mo". Niwon igbati awa siti mo kosi ohun ti nje idarijin ese mo bikose idajo Olorun, Kristiani e kiyesara.

## E SE AFARAWE AWON OMO REKABU

Awa olufokansin ni lati se afarawe awon omo Rekabu ti igboran won je inudidun fun Olorun nipa yiya kuro ninu mimu oti waini tabi oti lile gegebi ase baba nla won Jonadabu. (Jeremiah 35:14-19).

O se koko ki awa Kristiani oma gboran ni gbogbo igba nitori eri-okan. Nitori idi eyi e jeki ama gboran ki asi ma tele ase Olorun ni igbati o wo ati ni igbati o olodi si ife okan wa. Ki baba wa Orun le ri awon akitiyan wa ki osi pin ere fun wa ni igbati ako lero.

## Ose Keta: Osu Kini Ojo Ketadinlogun 2016

**Akori Oro** : Aigboran Apa keji

**Eko Kika:** Jeremiah 42: 1-18

## Awon Ijiya Aigboran

## Alaini anfani ati wo Ijoba Orun

Awon alaigboran enia won ki tele ilana Oluwa besini won ki fetisi ohun Re, eyiti koni jeki won wo Ile Ologo. Awon wonyi yio ni ipa ti won ninu adagun ti nfi ina ati sulfuru jo, eyiti nse iku keji (Ifihan 21;8).
Tori idi yi Kristiani eyi pada , ki esi ko lati ma gboran si ase Olorun laisi amulumala, ki eyin na le wa lara awon ti yio peju pese nibi ase asale igbeyawo odo aguntan Olorun.
Enikeni ti oba ti di atunbi nini Kristi ti kosi feki awon aseyori ati lala ohun jasi otubante ni lati bere sini gboran si Olorun lenu ki osi ma tele ase Re ni alai ye ese.

### Ibinu Olorun

Kristiani e mase jeki a tan yin, ibinu gbigbona Olorunni yio kun aiye gbogbo alaigboran ayafi ti won ba ronupiwada, ti won fi iberu kun okan won ti won si se ilaja pelu Olorun (Efesu 5:6).
Ara ninu Oluwa e mase je asiwere ninu emi, e masi se jeki enikeni o so yin di asiwere ninu emi. Nitori Olorun ki yio fi aye sile fun awawi nipa awon ese ti a ba se, ambotori ese aigboran.Ohun kan ti ale fi kapa aigboran ni igboran si ase, ilana ati ohun Oluwa. Eyiti yio jeki Oluwa so aiye wa di otun ki osi da gbogbo ikolo wa ninu ara ati emi pada ni pipe.

### Kosi Asala

Iwe mimo bibeli fi ye wa wipe otito ni awon oro ti  Olorun nran lati enu awon angeli, ti asi nfi iya ti o to je  awon okan ti ose irekoja ati aigboran nipa esan ti o to ti osi ye gegebi ise won (Heberu 2:2).

Ese yi fi mule wipe kosi asala kuro ninu ijiya aigboran bikose ki awa eda enia o gboran si ase Olorun lo, gegbi oro awon Yoruba ti o wipe kosi ona abuja lorun ope.

**Awon Alaigboran Oluso aguntan**

Gbogbo oluso aguntanti o ba ko lati gboran si ase Olorun, yio so ogbon, imo ati oye ti Emi mimo fifun won nu. Awon wonyi yio wa di ope ninu emi besini Satani yio si je won lere. Siwaju si awon oluso aguntan yi kiyo ri rere tabi se rere, besini agbo won yio tuka ni bibeli wi (Jeremiah 10:21). Ni afikun Olorun yio bere eje awon aguntan ti o sonu lowo iru oluso aguntan be, eyiti o tumo si wipe afikun ijiya tabi inira ni fun iru awon oluso aguntan be.
Ni ode oni, awon iru oluso agutan yi ma nto awon okunkun lo ki agbo won maba tu sugbon ni ikehin: iku esin ni won ma nku awon agbo won asi tuka nigbati asiri ba tu.

**Awon Ajalu ti Aigboran Nfa**

Gbogbo okan tiwon ba ko ilana Olorun sile ti won kosi tele ofin ti o fifun wa, gbogbo okan ti kose ife Re ti won kosi gba ohun Re gbo yio ge ika abamo je ni ikehin.Ni igbati awon arelu buburu yi ba nsele ninu aiye won.

- Ile won ati ona onje ojo won yio baje patapata.
- Won je ikoro ati majele nipa emi.
- Won yio tuka kakiri agbaiye, won yio si je ajoji ni ile ti o jina rere.
- Awon ota yio ma fi ida le won titi ti ao fi run won patapata.
- Ekun yio di ore korikosun won, besini ekun asun-dake koni kuro ni oju won. (Jeremiah 9:12-18)

Ti oko ba feki awon ajalu yi o bori re mase da agunla, mase se aiya re le tabi se agidi nipa sise ife okan re. Ni igbagbogbo wa ninu iberu Olorun, gboran si ase Re ki osi mase eyi ti o to ti osi ye niwaju Olorun.

**Awon Apejuwe Aigboran ninu Bibeli**

**Adamu ati Efa ( Genesisi 3)**

Adamu se aigboran si Olorun nipa kiko ehin si ase Olorun ti osi tele imoran Efa aya re. Igbese yi mu isoro nla ba awa iru omo re, ti osi fi aye gba ajaga wiwuwo ninu aiye wa. Atunbotan iwa aigboran Adamu ati Efa bi awon isele kan ti oa mu enu ba.

- Ipinya larin Olorun ati enia (Genesisi 3:23-24). A le Adamu ati aya re Efa kuro ninu ogba Edeni.
- A fi iran eda enia gegun (Genesisi 3:17-19). Olorun fi ile bu nitori aigboran Adamu wipe "Ninu oogun ojure ni iwo yio ma jeun titi iwo o fipada si ile"
- A fi iran obinrin gegun (Genesisi 3:16). Olorun fi awon obinrin re wipe " A so iponju ibimo re di pupo ati ninu ipoju ni iwoyio ma bimo"
- Enia ku nipa Emi. Ni igbati a le Adamu ati Efa kuro ninu ogba Edeni, won padanu ati ma ri Olorun ni ojukoju ti won si nba soro bi enia ti nba ore re soro. Lati igba na ko si eda enia kan ti o tun ni ore-ofe lati ri Olorun ni ojukoju mo bikose ninu Emi nipa ala, iran ati isipaya. Ayafi Mose Iranse Olorun ti o ri Ogo Olorun ti nrekoja.
- A fi Ota si arin Enia ati Satani (Genesisi 3:14-15). Olorun gbe ejo lailai ni gegun nitori ti o tan Adamu ohun Efa, o si fi ota si arin Iru omo re ati Satani.

## <u>Farao (Ekisodu Ori 2-7)</u>

Aigboran Farao ba oro aje Ile Egipti igbani je lopolopo, o si muki opo enia ara Egipiti so emi won nu. Nitori Farao se aiya le kosi jeki awon omo Israeli lo kuro larin won sugbon o feki won ma sin won niso gegebi eru. Ni soki ao mu enu ba awon ohun ti o ti idi re yo:

- Opa di ejo (Eksodu7:10-12)
- Omi di eje (Eksodu7:17-22)
- A fi opolo kolu ile Egipiti (Eksodu 8:1-7)
- A fi ina aso kolu ile Egipiti (Eksodu 8;16-19)
- A fi esinsin kolu ile Egipiti (Eksodu 8:20-24)
- Iku awon eran osin (Eksodu 9:1-5)
- A fi oowo kolu ile Egipiti (Eksodu 9:8-11)
- A fi yinyin ati ina kolu ile Egipiti (Eksodu 9:16-23)
- A fi eesu kolu ile Egipiti (Eksodu 10:12-15)
- A fi okunkun biribiri kolu ile Egipiti (Eksodu 10:21-23)
- Iku akobi omo jakejado ile Egipiti (Eksodu 12:28-30).

## Christ apostolic Miracle Ministry

## Ose Kerin: Osu Kini Ojo Kerinlelogun 2016

**Akori Oro** : Aigboran Apa keta

**Eko Kika:** Jeremiah 42: 1-18

### Akani (Josua ori 7)

Akani mu ninu awon ohun iyasoto ti Olorun ti pase wipe ki a ya si oto fun ohun, nipa aigboran Akani yi awon omo Israeli kole duro niwaju awon ota won. Awon ara Ai pa ninu awon omo Israeli besini awon toku sa ni iwaju awon ara Ai. (Josua 7:2-12)
Lehin Igbati Olorun ti pase ki a ya awon ohun kan soto fun Ohun. Akani nipase ojukokoro se aigboran si ase Olorun, o puro besini o seke ni dida ohun iyasoto mo nkan ini re. Akani yi pelu gbogbo ohun ini re ninu aiye ni a so ni okuta pa, asi dana sun won. (Josua 7:16-26)

### Oba Saulu (1 Samueli ori 13 & 15)

Oba Saulu se asise nla ati aigboran si Oluwa, o si padanu ite Israeli eyiti a gbe fun Dafidi ti nse aladugbo re ti o san ju lo. Siwaju si awon Saulu so ite Israeli nu titi aiyeraye, Saulu so ohun ti ako le ri lati ra tabi mu pada bo sipo nu, o so ogun iyebiye nu titi lailai.
Lakoko, oba Saulu se aigboran si Oluwa nipa riru ebo sisun, eyiti ko leto fun lati se bikose awon alufa (Samueli) toripe riru ebo sisun kise ise oba. (1 Samueli 13:9-14).

Lekeji oba Saulu ko pa ohun gbogbo ti awon ara Amaleki ni run gegebi ase Oluwa, bikose awon ohun ti koni laari. Saulu da Agagi oba awon ara amaleki si, o da awon aguntan, ewure ati malu daradara si pelu. Aigboran keji yi ni "odada ti o se ehin rakunmi".
Isele yi dun Oluwa wipe Saulu ko ti le ko eko nipa asise re akoko, debipe Oga-ogo soro wipe "Emi kanu gidigidi ti emi fi Saulu joba, nitori ti o ti yipada lehin mi, ko si mu oro mi se". (1 Samueli 15:10-23).

Lotito ni Saulu jewo fun Samueli wipe, ohun ti se: nitori ti ohun ti re ofin Oluwa koja ati oro Re: nitori ti ohun beru awon enia, ohun si gba ohun won gbo. Sugbon "aso koba Omoye mo, Omoye ti rin ihoho wo oja. (1 Samueli 15:24-29). Tori idi yi

mase jeki wahala tabi akitiyan enikeni mu o se aigboran si Olorun ti o fe o , ti o si nse anu fun o. Ni afikun dojuko etan tabi iwa awon elegbe re ti o le mu o se aigboran si ofin Olorun.

## Kiniun pa woli ti a ran lati ile Judah

Olorun ran woli kan lati ile Judah si oba Jeroboamu lati so ohun ti yio sele ni ojo iwaju ki o le yipada kuro ninu iwa eeri re si Oluwa. Oro ti a ran si Jeroboamu yi bi ninu, oba na owo re wipe "e mu" woli na. Owo ti oba na lati mu enia Olorun na si gbe lesekese, sugbon enia Olorun gba adura, a si mu owo oba bo si ipo re. (1 Awon oba 13:1-7).

Isoro enia Olorun yi bere ni igbati woli agba ti ngbe ninu ilu na tan wipe ki o ba ohun pada si ile ohun lati je ati lati mu. Woli lati Judah yi se aigboran si ase Olorun nitori ati te woli agba lorun. Lehin igbati Oluwa ti kilo fun wipe " ko gbodo jeun, ko gbodo mu ohunkohun ninu ilu na besini ko gbodo gba ona ti o ba wo ilu pada kuro ninu ilu na" (1 Awon oba 13:8-19).
Ara ninu Oluwa o dara ki a gbo ti Oluwa ju ti enia lo besini o dara ki a te Olorun lorun ju ki a te enia lorun lo. E jeki a ranti wipe Olorun ni o gbodo je akoko ninu ohun gbogbo ti a ba nse, e mase jeki igboran si enia eleran ara mu yin se aigboran si Oluwa; ki ibinu gbigbona Olorun ma ba wa si ori eyin ati iran yin.

A san ere aigboran fun woli Judah ni igbati kiniun pade re lona ti osi pa. Olorun feki gbogbo enia o keko lara asise woli na ni ofi jeki kiniun pa woli lai fowo kan ketekete re, kiniun yi kosi salo besini ko fa oku woli na ya sugbon o duro ti gegebi eleri ere aigboran re. (1 Awon oba 13:20-25).

Kristiani e jeki a mo daju wipe bi Olorun ba tile ti lo o ni awon ona kan lati se ise ami ati iyanu tabi ise iwosan ti o ni itumo: eyi ko tumo wipe o koni jiya awon iwa aigboran re. O dara lati ko ogbon lati ara asise elomiran nitori "eniti o jin si koto, ni o ko ara iyoku logbon". Ki o maba di wipe asise wa yio ni ipa buburu ti a kole pare tabi yi pada ninu aiye wa.

## Jona

Gbogbo wa ni a mo itan Jona ti Olorun ran si awon ara Ninefe lati kilo fun won nitori awon iwa ika won ati pelu idajo Olorun ti o setan lati wasi ori won. Sugbon Jona pinu lati sa kuro ni iwaju Oluwa, lati wo oko oju omi losi ilu Tarsisi.

A so Jona sinu omi, eja nla gbe Jona mi, nibe ni o gbe ronupiwada. Jona gba adura ati awe ojo meta si Olorun lati inu eja. Lotito ijiya ese Jona kere fun ese aigboran re, nitoripe o ronupiwada ki akoko to lo. (Jona 1:1-7)

Ara ninu Oluwa e mase jeki a dabi asiwere ti yio wipe ohun yio ronupiwada ese aigboran ohun "gegebi Jona ki akoko to lo". Nitoripe Olorun nikanni o le fi ironupiwada fun eda enia, iwo si le mari ore-ofe gba gegebi Jona.

## Christ apostolic Miracle Ministry

## Ose Karun: Osu Kini Ojo Kokanlelogbon 2016

**Akori Oro** : Aigboran Apa kerin

Eko Kika: Jeremiah 42: 1-18

## Awon Iponju ti Aigboran nfa wonu aiye enia (Lefitiku 26:14-43)

Awon Yoruba wipe "ogun asotele ki pa aro ti o ba gbon" nitori idi eyi ao se ayewo ni finifini awon ijiya ti o romo aigboran lati inu iwe Lefitiku.
Iwe yi so di mimo wipe enikeni tiko ba ti feti sile lati gbo ti Olorun tabi gboran si ofin Re. Pelupelu gbogbo okan ti won ba da majemu Re tabi kehin si majemu nla Re, awon ti won ko si bowo fun ase Re, ti won ngan ilana Re , ohun ti o wu ki won je ao fi awon iponju wonyi bo won bi o ti wu ki ori:

- Won yio ni ajakale-arun ati aisan ojojo gbigbona eyiti yio jeki oju won ma su bayiibayii,ti osi je wipe emi won yio ma yoro/joro diedie. Itumo ni wipe bi awon eda wonyi ko ba kiyesara won yio so emi won nu.
- Ohun eru nla yio sele si won lojiji, oro aje won yio si fori sanpa atipe won yio ri inira tabi ki afi eto won du won.
- Olorun yio lodi si gbogbo awon alaigboran pelu ibinu, yio se oju Re lodi si awon alaigboran fun isubu, besini awon ota yio si ma segun awon alaigboran.
- Awon ti o korira awon alaigboran ni yio mase olori won, besini awon alaigboran yio si sa ni igbati enikeni ko le won.
- Oluwa yio se agbara igberaga won, ao se oju orun won dabi irin (nipa aisi ojo tabi ogbe-le) ati ile won dabi ide ( kosi iye ajile ti won le lo ti yio mu ikore yanturu jade).
- Gbogbo ise won yio si je lori asan, nitori ile won ki yio mu ibisi re wa, besini awon igi ile won ki yio so eso won (gbogbo ona atije atimu won ni yio baje)
- Oluwa yio ran eranko si won ti yio ma pa won ni omo, ti yio si ma run awon eran osin won. Eyi ni yio mu won dinku, ti yio si so awon opopo won di ahoro ( orisirisi isele aburu ti yio muki awon enia sa kuro ni awon agbegbe won).
- Ogun, ida ati ajakale arun yio la ile won ja, yio si so di ahoro.

- Ao se opa onje won, iyan yio si wa ni ile won ati owon gogo awon ohun amaiye derun.
- Bi won ba tile wa laaye, won ki yio je ajeyo tabi ajeseku, besini a ki yio te ife won lorun pelu ohun rere.
- Awon ogun ajoji yio gba ile won, Olorun yio tu won ka si awon orile-ede miran besini yio fi ohun ija oloro Re ba won ja.
- Oluwa yio so won di eni yeye ni ile awon ota won,won yio si ma gbe ninu ipaiya ni igba gbogbo.
- Won koni ni agbara tabi Igboya lati duro niwaju awon ota won.
- Won yio si ku ni ile ajoji, awon ota won yio si je won run.
- Awon ti o ku ninu won yio si joro ninu ese won, ni ile awon ota won.

Gbogbo awon iponju ti ati so nipa re ni yio wa si ori awon alaigboran, titi ti won yio fi re okan aigboran won sile, ti won yio si gba wipe awon jebi, eyiti yio mu won gbe igbese lati ma gboran si ase Olorun.
O se pataki wipe ki ama fi owo ro iwe Lefitiku yi sehin sugbon ki a ka ninu emi. Ti aba se eyi ao ri daju wipe awon ti o ni imo larin wa, koni tapa si ase Oluwa tabi se aigboran si Olorun mo. E jeki a ko eko lara awon omo Israeli igbani, ki aba le kun fun eru Oga-ogo ki a si paiya atise aigboran si eleda wa.

## Awon eegun aigboran

Awon eegun aigboran ni ao ri ka ninu iwe Deuteronomi (Deuteronomi 28:15-68). A ni lati ka awon ese bibeli yi lati le ni oye ese ribiti ti a npe ni aigboran. Awon eegun ti o wa ninu iwe yi koni wasi imuse ninu aiye wa tori o da mi loju wipe gbogbo wa ni ao se atunse, ti ao si yi pada si igbe aiye otun.

## Ni Ipari (Awon ara Romu 10:21)

Lakotan Kristiani Olorun si apa anu Re, o si na owo alafia Re si wa. Nitirina e mase jeki a te siwaju ninu iwa aiye nipa iwa aigboran gbogbo igba.
E dake gbigbo Olorun lenu, sugbon ki a te siwaju ninu iwa jeje ati irele. Ki gbogbo akitiyan lati gba wa la maba je lori asan, ki oju si le ti Satani ni gbangba lori oro aiye wa.